# Subtitle Format Yoruba

### Chapter 1 Introduction

Ọna ti oyun inu ọmọ enia ti o ni ẹyin kekere kanlolo ngba ti agbalagba enia ti o ni ẹgbẹrun lọna aadọjọ ẹyin keekeke jẹ ifarahan ti o yanilẹnu julọ ninu ohun gbogbo ti o wa laye.

Awon oluwadi ti mọ bayi wipe, pupọ ninu awæn isẹ ojoojumọ ti ara agbalagba enia nse ni a ti filelẹ lati inu oyun wa – nigba pupọ, ki a to bi ni s’aye.

Akoko idagbasoke ki ọmọ to o w’aye ni o tubọ nye ni sii gẹgẹbi akoko ipalẹmọ, ninu eyiti ọmọ enia ti o sẹsẹ ndagbasoke njẹ ere orisirisi awọn ẹya-ara, ti o si nfi orisirisi ọgbọn han, eyiti yio lo fun wiwa laaye lẹhin ti a ba bii tan.

### Chapter 2 Terminology

Oyun lara ọmọ enia ma ngba to ọsẹ mejidinlogoji ti a ba kaa lati igbati idapọ ba ti w’aye laarin ẹyin ọkunrin ati obirin, tabi lati igbati enia loyun, titi di asiko ibimọ.

Ni ọsẹ mẹjọ ekini lẹhin idapọ ẹyin ọkunrin ati obirin, ọmọ enia ti i ndagbasoke ninu ni a npe ni ẹmubirayoo, eyiti o tumọ si “idagbasoke ninu." Akoko yi, ti a npe ni akoko ẹmubirayoo, ma nfarahan nipa fifi awọn orisirisi ẹya-ara le lẹ.

Lati igbati ọsẹ mẹjọ ba kọja, titi di opin iloyun, "ọmọ enia ti ndagbasoke ninu yi ni a npe ni fitọọsi,” itumọ eyiti nse "ọmọ ti a ko i tii bi." Ni akoko yi, eyiti a npe ni akoko fitọọsi, gbogbo ẹya-ara ọmọ naa yio dagbasoke sii, wọn yio si maa sisẹ.

Gbogbo awọn akoko iloyun ti o wa ninu eto yi ntọka si akoko ti o bẹrẹ lati igbati idapọ ẹyin ọkọ ati aya ti w’aye.

## The Embryonic Period (The First 8 Weeks)

***Embryonic Development: The First 4 Weeks***

### Chapter 3 Fertilization

Bi a ba nsọrọ nipa awọn ohun alaaye, "idagbasoke enia bẹrẹ lati igbati idapọ ba w’aye laarin ẹyin ọkunrin ati obirin," nigbati ọkunrin ati obirin ba da mẹtaleloogun ninu awọn eroja ti o wa ninu ẹya-ara wọn pọ, nipasẹ idapọ ẹya-ara ti o wa fun ọmọ bibi.

Ẹya-ara ti o wa fun ọmọ bibi ninu ara obirin ni a npe ni "ẹyin" Sugbọn ohun ti o yẹ ki a pee ni oosaiti.

Bakanna, ẹya-ara ti o wa fun ọmọ bibi lara ọkunrin ni a npe ni "sipaamu," Sugbọn ọrọ ti o dara julọ fun eyi ni sipamatosoonu.

Lẹhin ti ẹyin ba ti jade tan kuro ninu apo ẹyin obirin nipasẹ ọna ti a npe ni ofulesan, ẹyin naa ati sipamatosoonu yio dapọ ninu ọkan lara okun ile ọmọ, eyiti a npe ni okun Falopiani.

Awọn okun ile ọmọ yi ni o so ile ẹyin obirin pọ mọ ile ọmọ tabi wohunbu.

Abajade idapọ yi ni nfa oyun, eyiti a npe ni saigọọti, itumọ eyiti nṢe "isopọ tabi idapọ sọkan."

## Chapter 4   DNA, Cell Division, and Early Pregnancy Factor (EPF)

### DNA

Awọn eroja mẹrindinlaadọta ti o wa ninu saigọọti duro fun ekini ninu awọn alailẹgbẹ eto igbesi aye ọmọ enia titun. Eto pataki yi wa ninu awọn ohun kan ninu agọ ara ti a npe ni DNA. Ninu wọn ni asẹ fun idagbasoke gbogbo ara enia wa.

Awọn ohun ti a npe ni DNA yi farajọ akaba ti o lọ pọ, ti a npe ni dọbulu hẹlikisi. Lara akasọ ara akaba naa ni awọn ohun kan, ti a npe ni guanini, sitosini, adinini, ati taamini wa.

Guanini yi le darapọ mọ sitosini nikan, adinini si le darapọ mọ taamini. Ọkọọkan ninu awọn ẹyin keekeke ti a fi da enia ni o ni ọkẹ aimoye awọn ohun ti a darukọ loke wọnyi ninu.

DNA inu ọkan ninu awọn ẹyin keekeke ti a fi da enia yi ni oriṢiriṢi alaye ninu, ti o jẹ wipe, bi a ba fẹ kọ wọn silẹ ni ọrọ, lẹta ekini ninu ọkọọkan awọn ohun ti a darukọ wọnyi yio gba oju ewe iwe ti o to miliọnu kan ati aabọ!

Bi a ba gbe wọn si ẹgbẹ ara wọn, DNA inu okansoso ninu awọn ẹyin keekeke wọnyi yio gun to iwọn ẹsẹ mẹta ati diẹ tabi mita kan.

Bi a ba le tu gbogbo DNA yi palẹ ninu ọkẹ aimọye ẹyin keekeke ti o wa ni ara agbalagba enia, yio gun to iwọn mẹtalelọgọta biliọnu maili. Gigun rẹ yi to ki a rin irin ajo lati aye lọ si ibiti oorun wa, ati ki a pada ni ọọdun igba, o le ni ogoji.

### Cell Division

O fẹrẹ to wakati mẹrinleloogun si ọgbọn wakati lẹhin idapọ ẹyin ọkunrin ati obirin, ki saigọọti to pari pinpin si meji rẹ akọkọ. Nipasẹ ọna ti a npe ni maitosisi, ẹyin kan yio pin si meji,meji yio pin si mẹrin, ati bẹẹbẹẹ lọ.

### Early Pregnancy Factor (EPF)

Laarin wakati mẹrinleloogun si wakati mejidinlaadọta lẹhin ti idapọ ti waye, a le sọ daju pe oyun ti wa nipo, nipasẹ ọkan ninu awọn ohun kan ti a npe ni homonu, eyiti orukọ rẹ njẹ "olufihan oyun inu titun", ti o wa ninu ẹjẹ iya ọmọ.

## Chapter 5   Early Stages (Morula and Blastocyst) and Stem Cells

Laarin ọjọ mẹta si mẹrin lẹhin idapọ ẹyin ọkunrin ati obirin, ẹyin naa yio maa pin si ọna pupọ, wọn a ri rogodo, a si npe oyun inu naa nisisiyi ni morula.

Laarin ọjọ mẹrin si marun, iho kan yio waye laarin awọn ẹyin rogodo wọnyi, a si npe oyun inu naa nisisiyi ni bilasitosisiti.

Awọn ẹyin keekeke ti o wa ninu bilasitosisiti yi ni a npe ni akojọpọ ẹyin ti inu, eyiti yio ko ara wọn jọ pọ lati di ori, ara, ati awọn ẹya ara miran ti o Ṣe pataki fun idagbasoke ọmọ enia.

Awọn ẹyin ti a fi ns'ẹda enia, eyiti o wa ninu akojọpọ ẹyin ti inu yi ni a npe ni ẹyin oyun ti o l'ẹka, nitori wipe wọn lagbara lati di ọkan ninu iru awọn orisirisi ẹyin keekeke ti o le ni igba, eyiti o wa ni ara ọmọ enia.

## Chapter 6   1 to 1½ Weeks: Implantation and Human Chorionic Gonadotropin (hCG)

Nigbati o ba kuro ninu okun ile ọmọ, oyun inu titun yi yio gbin ara rẹ sinu ẹran ara ti o wa ni ayika ile ọmọ iya rẹ. Ilana yi, ti a npe ni gbigbin nkan, ma nbẹrẹ ni ọjọ kẹfa, yio si pari ni ọjọ kẹwa si ekejila lẹhin idapọ ẹyin ọkunrin ati obirin.

Ẹyin keekeke ara oyun inu ti ndagba yi a bẹrẹ sii mu orisi homonu kan jade, eyiti a npe ni hCG, eyiti o si ma nfarahan nigbati a ba Ṣe ayewo lati mọ boya oyun ti duro.

HCG ma ntọ homonu ara iya lati da nkan osu duro, ki oyun baa le dagbasoke siwaju sii.

## Chapter 7   The Placenta and Umbilical Cord

Lẹhin ti oyun ba ti gbin ara rẹ si ile ọmọ iya rẹ tan, awọn ẹyin keekeke ti o wa l'ẹba bilasitosisiti yi yio di lara ẹya ohun ti a npe ni ibi-ọmọ, eyiti o so ẹya ara ti ngbe ẹjẹ yika ara iya pọ mọ ti ọmọ inu oyun.

Ibi-ọmọ yi a ma gbe atẹgun, ounjẹ, homonu ati oogun lati ara iya lọ si ara ọmọ inu oyun ti ndagba naa; o si tun ma nmu idọti ara kuro; kii si jẹki ẹjẹ ara iya dapọ mọ ẹjẹ ara ọmọ inu oyun.

Ibi-ọmọ ma nmu awọn homonu jade, o si ma nmu ki iwọn otutu tabi ooru ara ọmọ inu oyun o pọ diẹ ju ti ara iya rẹ lọ.

Ohun ti a fi so ibi-ọmọ pọ mọ oyun inu ni okun ibi-ọmọ.

A le fi ọna ti ibi-ọmọ ngba se atilẹhin fun ẹmi ọmọ inu oyun we iyara ti a ti nse itọju awọn enia ti o wa labẹ ewu, ni ile iwosan igbalode.

## Chapter 8   Nutrition and Protection

Lẹhin ọsẹ kan, ẹyin keekeke ti o wa lara akojọpọ ẹyin inu yio di awọ fẹlẹfẹlẹ meji ti a npe ni aipobilasiti ati ẹpibilasiti.

Aipobilasiti yi ni yio di ohun ti a npe ni apo ẹyin, eyiti o jẹ ọkan lara awọn ẹya ara, nipasẹ eyiti iya yio maa gba fun oyun inu rẹ l'ounjẹ.

Ẹyin keekeke lati ara ẹpibilasiti yio di awọ fẹlẹfẹlẹ kan ti a npe ni aminiọnu, ninu eyiti ọmọ inu oyun ti a ṢẹṢẹ ni, ati ọmọ inu oyun ti o ti le ni ọsẹ mẹjọ yio ti maa dagbasoke titi di akoko ibimọ.

**Chapter 9   2 to 4 Weeks: Germ Layers and Organ Formation**

Lẹhin ọsẹ meji ati aabọ, ẹpibilasiti yio ti di oriṢi ẹya ara mẹta, tabi awọ fẹlẹfẹlẹ, ti a npe ni ẹkitodaamu, ẹndodaamu, ati mẹsodaamu.

Ekitodaamu yio di awọn oriṢiriṢi ẹya ara bii ọpọlọ, ọpa-ẹhin, iṢan-ara, awọ-ara, eekanna, ati irun.

Ẹndodaamu yio di awọ ti a fi tẹ inu ẹya ara ti atẹgun ngba lara enia ati ti inu ẹya ara ti ounjẹ ngba, yio si tun di lara oriṢiriṢi awọn ẹya ara miran bii ẹdọ ati ẹya ara ti oronro ngbe inu rẹ.

Mẹsodaamu yio di ọkan, kidinrin, egungun, kerekere, iṢan, ẹjẹ, ati awọn ẹya miran.

Lẹhin ọsẹ mẹta ọpọlọ yio pin si ọna mẹta ọtọọtọ ti a npe ni ọpọlọ iwaju, ọpọlọ aarin, ati ọpọlọ ẹhin.

Idagbasoke awọn ẹya ara ti ngbe ẹjẹ ati ounjẹ kaakiri ara ti bẹrẹ pẹlu.

Bi ẹjẹ akọkọ ba ti de inu apo ẹyin, iho ara ti ẹjẹ ngba yio farahan kaakiri lara ọmọ inu oyun naa, bẹẹ si ni ọkan, eyiti o ri rogodo, yio farahan bakanna.

O fẹrẹ jẹ lẹsẹkanna ni ọkan ti ndagbasoke ni kiakia yi yio sẹpo sori ara rẹ, bẹẹ si ni apo ọtọọtọ yio maa waye laarin ọkan naa.

Ọkan naa yio bẹrẹ sii mi lati ọsẹ kẹta ati ọjọ kan lẹhin idapọ ẹyin ọkọ ati aya.

Ẹya ara ti ngbe ẹjẹ kiri gbogbo ara jẹ ẹya ara akọkọ, tabi akojọpọ awọn ẹya ara ti o jọ ara wọn lati bẹrẹ sii ṢiṢẹ.

**Chapter 10   3 to 4 Weeks: The Folding of the Embryo**

Larin ọsẹ mẹta si mẹrin, awọn eto ẹya ara yio yanju, gẹgẹbi ọpọlọ, ọpa-ẹhin, ati ọkan ọmọ inu oyun naa, eyiti a le fi irọrun damọ lati ẹgbẹ apo ẹyin.

Idagbasoke yi ma nmu ki oyun inu ti o ti Ṣe pẹrẹsẹ tẹlẹ ri ki o sẹpo. Ilana yi a maa so lara apo ẹyin pọ mọ awọ ti a fi tẹ inu ẹya ara ti ngbe ounjẹ kaakiri ara enia, wọn yio si di aya ati inu ikun ọmọ inu oyun ti ndagba naa.

*Embryonic Development: 4 to 6 Weeks*

## Chapter 11 4 Weeks: Amniotic Fluid

Ni ọsẹ kẹrin, omi-ara ti o mọ tonitoni yi yio san yika ọmọ inu oyun ninu apo ile ọmọ. Omi ti ko ni abawọn yi, ti a npe ni omira, ma ndaabobo oyun inu lọwọ ipalara.

## Chapter 12 The Heart in Action

Ọkan enia ma nmi niwọn igba mẹtalelaadọfa laarin isẹju kan.

Sakiyesi bi awọ ara ọkan naa ti nyipada bi ẹjẹ ti nwọ inu awọn iho rẹ, ti o si njade.

Ọkan enia maa nmi niwọn igba mẹrinlelaadọta miliọnu ki a to bi ni, ati niwọn igba miliọnu mẹta, o le diẹ ni igbesi aye enia ti o pe ọmọ ọgọrin ọdun.

## Chapter 13 Brain Growth

Idagbasoke ọpọlọ ma nfi ara han nipa bi iyatọ se nwa ninu irisi ọpọlọ iwaju, ọpọlọ aarin, ati ọpọlọ ẹhin.

## Chapter 14 Limb Buds

Ọwọ ati ẹsẹ yio bẹrẹ sii yọ jade nigbati idi wọn ba farahan ni ọsẹ kẹrin.

Awọ ara ọmọ inu oyun naa ni asiko yi yio mọ gaara nitori pe ko nipọn pupọ.

Bi awọ ara naa se nnipọn sii, ni mimọ ti o mọ yio maa dinku, eyiti o tumọ si wipe a le maa wo bi awọn ẹya inu ara ti ndagba, fun osu kan sii.

## Chapter 15 5 Weeks: Cerebral Hemispheres

Laarin ọsẹ kẹrin si ikarun, ọpọlọ yio maa dagbasoke ni kiakia sii, yio si pin si ọna marun ọtọọtọ.

Ori jẹ iwọn kan ninu idamẹta gbogbo ara ọmọ inu oyun naa.

Ọpọlọ iwaju yio gba aaye ti o pọ fun ara rẹ, yio si di ẹya ti o tobi ju ninu ọpọlọ.

Awọn iṢẹ ti ọpọlọ iwaju yi wa fun ni ironu, ẹkọ kikọ, iranti nkan, ọrọ sisọ, iriran, igbọran, gbigbe ọwọ tabi ẹsẹ, ati yiyanju ọran ti o Ṣoro.

## Chapter 16   Major Airways

Ninu ẹya ara ti ngbe atẹgun kaakiri ara, iho ti atẹgun ngba pin si ọna meji, ni apa ọtun ati apa osi, eyi si ni yio so ọna ọfun pọ mọ ẹdọforo.

## Chapter 17   Liver and Kidneys

Sakiyesi ẹdọ nla ti o gba aaye ti o pọ ninu ikun, ni abẹ ọkan ti nmi naa.

Kidirin ti yio wa titi aye yio farahan ni ọsẹ karun.

## Chapter 18   Yolk Sac and Germ Cells

Ninu apo ẹyin ni awọn yin keekeke fun ọmọ bibi, eyiti a npe ni jamu sẹẹli, wa. Ni ọsẹ karun, awọn ẹyin keekeke wọnyi yio lọ si ẹya ara ti o wa fun ọmọ bibi, eyiti o wa l'ẹgbẹ kidinrin.

## Chapter 19   Hand Plates and Cartilage

Bakanna, ni ọsẹ karun, atẹlẹwọ ọmọ inu oyun naa yio bẹrẹ sii farahan, kerekere yio si bẹrẹ si ni farahan lati ọṢu karun ati aabọ.

Ni bayi, a o Ṣakiyesi atẹlẹwọ ti ọwọ osi ati ti ọrun ọwọ, ni ọsẹ karun ati ọjọ mẹfa.

### *Embryonic Development: 6 to 8 Weeks*

## Chapter 20   6 Weeks: Motion and Sensation

Ni ọsẹ kẹfa, aaye ti ọpọlọ iwaju gba yio maa tobi sii ni ọna ti o ya ju awọn ẹya ọpọlọ yoku lọ.

Ọmọ inu oyun naa yio bẹrẹ sii ni yi sihin sọhun. Iru yiyi sihin sọhun yi Ṣe pataki lati mu ilọsiwaju ba idagbasoke iṢan ara.

Bi a ba f'ọwọ kan ẹnu rẹ, ọmọ inu oyun naa yio fa ori rẹ mọra lọgan.

## Chapter 21   The External Ear and Blood Cell Formation

Eti naa ti nhu jade.

Ni ọsẹ kẹfa, ẹjẹ yio ti maa kojọpọ ninu ẹdọ, ninu ibiti awọn ohun kan ti ma ndaabobo ara lọwọ arun wa. Awọn ohun ti ndaabobo ara wọnyi jẹ koko lara apapọ awọn ẹya ara tii ma ba arun ja lara enia.]

## Chapter 22 The Diaphragm and Intestines

Ẹran ara ti o wa ni agbedemeji aya ati ikun, eyiti o jẹ ẹran ara ti enia fi nmi, yio ti farahan ni ọsẹ kẹfa.

Apa kan lara ikun yio wu jade fun igba diẹ sinu okun ibi-ọmọ. Ilana yi, eyiti i ma Ṣẹlẹ nigbagbogbo, ni a npe ni ifun yiyọjade ni ara enia. eyi a si maa fi aaye silẹ fun awọn ẹya ara miran ninu ikun.

## Chapter 23 Hand Plates and Brainwaves

Ni ọsẹ kẹfa, atẹlẹwọ yio di pẹrẹsẹ.

Ọpọlọ yio ti lagbara lati ronu lati bi ọsẹ karun ati ọjọ meji.

## Chapter 24 Nipple Formation

Awọn sonso ori ọmu yio yọ si aya, lẹhin eyiti wọn yio lọ si ibiti o yẹ ki wọn o duro si ni ookan-aya.

## Chapter 25 Limb Development

Ni ọsẹ kẹfa ati aabọ, awọn igunpa ọwọ yio ti yanju, aami ori ika ọwọ yio ti maa han, enia si le maa wo ọwọ naa bi o ti nmi.

Dida egungun ara, eyiti a npe ni osifikesan yio bẹrẹ lati ibi egungun ejika, eyiti a npe ni egungun kọla, ati egungun oke ati isalẹ agbọn ẹnu.

## Chapter 26 7 Weeks: Hiccups and Startle Response

A o ti sakiyesi wipe ọmọ inu oyun nse osuke, ki o too to ọsẹ keje.

A le Ṣakiyesi bi ọmọ inu oyun ti ngbe ẹsẹ rẹ, nigbakugba ti ohun kan ba dẹru baa.

## Chapter 27 The Maturing Heart

Ọkan ọmọ naa, eyiti o pin si ọna mẹrin, yio ti dagbasoke tan. Ọkan naa yio maa mi ni iwọn igba ti o to ẹẹmẹtadinlaadọsan laarin iṣẹju kan.

Agbara ti ọkan ọmọ naa ni, eyiti a se akiyesi rẹ ni ọsẹ meje aabọ, fihan wipe eyi fẹrẹ ba ti agbalagba enia dọgba.

## Chapter 28 Ovaries and Eyes

Bi o ba jẹ obirin, a le da apo ẹyin rẹ mọ lati ọsẹ keje.

Ni ọsẹ meje ati aabọ, ohun ti a npe ni rẹtina ninu oju ni a le se akiyesi rẹ yekeyeke, awọn ipenpeju naa si ti bẹrẹ sii ni tobi sii.

## Chapter 29 Fingers and Toes

Awọn ika ọwọ wa lọtọ, awọn ọmọ-ika ẹsẹ si so pọ ni isalẹ.

Ọwọ ti Ṣee papọ soju kan, bẹẹ naa si ni ẹsẹ.

Orunkun naa ti wa nipo.

*The 8-Week Embryo*

## Chapter 30 8 Weeks: Brain Development

Ni ọsẹ kẹjọ, ọpọlọ ti dagbasoke daada, o si jẹ iwọn idaji ninu gbogbo ara.

Idagbasoke yio maa tẹsiwaju ni kiakia.

## Chapter 31 Right- and Left-Handedness

Ni ọsẹ kẹjọ, iwọn ida marundinlọgọrin ninu ọgọrun ọmọ inu oyun ni maa lo ọwọ ọtun. Awọn yoku ni a le pin si awọn ti yio lo ọwọ osi, ati awọn ti yio lo mejeeji. Eyi ni o kọkọ fi iwa lilo ọwọ ọtun tabi ọwọ osi han.

## Chapter 32 Rolling Over

Iwe ẹkọ nipa ilera awọn ọmọde se apejuwe “yiyirapada ọmọde” gẹgẹbi iṢẹlẹ tii maa waye laarin ọsẹ kẹwa si ogun ọsẹ lẹhin ibimọ. sugbọn iru iwa ti o yanilẹnu yi ma nsaba waye nibiti agbara ti nfa ohun gbogbo walẹ ko ti pọ, ninu apo ile-ọmọ, eyiti omi kun inu rẹ. Aini agbara ti o pọ to lati bori agbara ti nfa ohun gbogbo walẹ yi ni ayika ti o yatọ si ti ile-ọmọ, ni ko le jẹki ọmọ ti a sẹsẹ bi le yi ara rẹ pada.

Ọmọ inu oyun naa ti le se ohun pupọ ni akoko yi.

O le maa yi sihin sọhun pẹlu ilọra tabi irọrun, lẹẹkọkan tabi leralera, lati inu wa tabi lairotẹlẹ.

Yiyi ori, nina ọrun, ati kika ọwọ ko sibi ori ma nwaye ni igba pupọ.

Bi a ba fọwọ kan-an, ọmọ inu oyun naa yio yara di oju rẹ, yio gbe agbọn rẹ, yio ma wa ohun ti o le dimu, yio si ma na ika ẹsẹ rẹ.

### Chapter 33   Eyelid Fusion

Laarin ọsẹ keje si ikẹjọ, ipenpeju oke ati isalẹ yio bo oju ọmọ inu oyun naa, yio si so pọ ni ẹgbẹ kan.

### Chapter 34   "Breathing" Motion and Urination

Biotilẹjẹpe ko si atẹgun ninu apo ile-ọmọ, ọmọ inu oyun naa yio ti bẹrẹ sii mi lati ọsẹ kẹjọ.

Ni asiko yi, kidinrin rẹ yio ti maa mu itọ jade sinu omi ti o wa ninu apo ile-ọmọ.

Ni ara ọmọ inu oyun ti o jẹ ọkunrin, koro ẹpọn ti ndagba lara rẹ yio bẹrẹ si mu ohun ti a npe ni tẹsitositẹrooni jade.

### Chapter 35   The Limbs and Skin

Awọn egungun ara, orike ara, ẹran ara, isan ara, ati awọn ẹya ara ti ẹjẹ ngba san kaakiri, eyiti o wa ni ọwọ ati ẹsẹ fi ara jọ ti agbalagba.

Ni ọsẹ kẹjọ, awọ ara yio bẹrẹ si nipọn sii, ki yio si mọ gaara mọ.

Irun yio hu si oke oju ati ayika ẹnu.

### Chapter 36   Summary of the First 8 Weeks

Ọsẹ kẹjọ ni opin akoko ẹmubirayoo.

Ni asiko yi,ọmọ inu oyun naa ti dagbasoke lati ẹyin kekere kanṢoṢo si ọkẹ aimọye ẹyin keekeke, eyiti yio di awọn orisirisi ẹya ara miran ti o le ni ẹgbẹrun mẹrin.

Ọmọ inu oyun naa ni ida aadọrun ninu ọgọrun ẹya ara agbalagba enia.

## The Fetal Period (8 Weeks through Birth)

### Chapter 37   9 Weeks: Swallows, Sighs, and Stretches

Akoko fitọsi yi wa titi di igbati a o bi ọmọ naa.

Ni ọsẹ kẹsan, ọmọ inu oyun naa yio bẹrẹ sii mu ika rẹ, o si le gbe omi inu apo ile-ọmọ mi.

Ọmọ inu oyun naa le di nkan mu, o le mi ori rẹ siwaju ati sẹhin, o le la ẹnu rẹ, o le gbe ahọn rẹ, o le poṢe, osi le na.

Isan-ara ti o wa ni oju, atẹlẹwọ, ati atẹlẹsẹ ma nmọ ọ lara bi a ba fi ọwọ kan wọn.

“Bi a ba rọra fi ọwọ kan gigise,” ọmọ inu oyun yio rọ ibadi rẹ ati orunkun rẹ yio si lẹ ọmọ-ika ẹsẹ rẹ pọ

Ipenpeju ọmọ naa yio bo oju rẹ patapata.

Ninu apoti ifọhun ti o wa ni ọna-ọfun, ifarahan awọn edidi ni yio fihan wipe awọn okun ti a fi nfọhun ti ndagbasoke.

Ni ara ọmọ inu oyun ti o jẹ obirin, a ti le da apo ile-ọmọ mọ, awọn ẹyin ile-ọmọ ti ko i tii dagba tan, ti a npe ni hugonia wa ninu apo ile-ọmọ naa, nibiti wọn ti npin si ọna pupọ.

Awọn ẹya ara ti o wa fun ọmọ bibi yio ma farahan gẹgẹbi ẹya ara ọkunrin tabi ti obirin.

## Chapter 38 10 Weeks: Rolls Eyes and Yawns, Fingernails & Fingerprints

Orisirisi awọn idagbasoke ti nwaye laarin ọsẹ kẹsan si ikẹwa yio mu ki ara ọmọ naa o tobi sii bi iwọn marundinlọgọrin ninu ọgọrun.

Ni ọsẹ kẹwa, bi a ba fọwọkan ipenpeju ọmọ naa, yio yi ẹyin-oju rẹ si isalẹ.

Ọmọ inu oyun naa le yan, o le la ẹnu rẹ, ki o si paade.

Ọpọlọpọ ọmọ inu oyun ni maa nmu atanpako wọn ọtun.

Apa kan lara ifun, nibiti ibi-ọmọ wa yio ma wọnu ara pada si inu ikun.

Awọn egungun yio maa le sii.

Eekanna ọwọ ati ti ẹsẹ yio bẹrẹ sii hu jade.

Aami ori ika-ọwọ yio bẹrẹ sii han ni ọsẹ kẹwa lẹhin idapọ ọkunrin ati obirin. Aami yi ni a fi nda enia mọ ni gbigbo ọjọ aye rẹ.

## Chapter 39 11 Weeks: Absorbs Glucose and Water

Ni ọsẹ kọkanla, imu ati ete ti yọ jade daradara. Gẹgẹbi oṢe wa ni awọn ẹya ara yoku, irisi wọn yio ma yipada lati igba de igba, ninu igbesi-aye ọmọ enia naa.

Ifun inu yio bẹrẹ sii fa Ṣuga ati omi ti ọmọ inu oyun naa ba gbemi mu.

Biotilẹjẹpe ẹya akọ tabi abo ma nfarahan lati igbati idapọ ẹyin ọkọ ati aya ba ti waye, awọn ẹya ara ti o wa fun ọmọ bibi ni a le damọ bayi, gẹgẹ bi ẹya ti akọ tabi ti abo.

**Chapter 40 3 to 4 Months (12 to 16 Weeks): Taste Buds, Jaw Motion, Rooting Reflex, Quickening**

Laarin ọsẹ kọkanla si ikejila, iwọn ara ọmọ inu oyun naa yio pọ sii pẹlu iwọn ọgọta ninu ọgọrun.

Ọsẹ kejila ni opin ipele akọkọ ninu mẹta, igba ti obirin fi nloyun.

Awọn ohun ti a fi nse itọwo ounjẹ yio bo gbogbo ayika ẹnu. Bi a ba bimọ naa tan, awọn ohun itọwo wọnyi yioṢi wa nipo lori ahọn nikan, ati ni oke ẹnu.

Igbẹ yiya yio bẹrẹ lati bi ọsẹ kejila, yio si tẹsiwaju fun bi ọsẹ mẹfa sii.

Ohun akọkọ tii ma jade lati idi ọmọ inu oyun ati ọmọ ti a ṢẹṢẹ bi ni a npe ni mẹkoniọmu. Ninu rẹ ni a ti le ri awọn ohun ti nmu ounjẹ da, ounjẹ tii mu ni dagbasoke, ati awọn ẹyin keekeke ti ko wulo mọ, eyiti o jade lati inu ẹya ara ti ngbe ounjẹ kaakiri ara.

Ni ọsẹ kejila, gigun ọwọ ti fẹrẹ to iwọn ti o yẹ fun ara. Ẹsẹ ma npọ diẹ sii ki o to gun to bi o ti yẹ fun ara.

Bi a ba yọ ti ẹhin ati oke ori kuro, gbogbo ara ọmọ inu oyun naa ni o ma nfesi, bi a ba rọra fọwọ kan wọn.

Awọn idagbasoke ti o ba ti ẹya akọ tabi abo lọ yio farahan fun igba akọkọ. Fun apẹẹrẹ, ọmọ obirin ma njẹ ẹnu rẹ bakan ju ọmọ ọkunrin lọ.

Yatọ si bi o ti ma nṢe tẹlẹ ri, bi a ba fọwọkan ẹnu ọmọ inu oyun yi, yio yirapada si ọkankan ibiti a ti fọwọkan-an, yio si la ẹnu rẹ. Iru ifesi bayi ni a npe ni “rutini rifulẹkisi” o si ma ntẹsiwaju lẹhin ti ọmọ naa ba d’aye tan, ninu eyiti i ma ran ọmọ lọwọ lati wa ibiti ori-ọmu iya rẹ wa, nigbati o ba fẹ mu ọmu.

Oju yio maa dagbasoke sii, bi ọra ti nkun gbogbo ẹrẹkẹ, bẹẹ si ni ehin naa yio bẹrẹ sii dagbasoke.

Ni ọsẹ kẹẹdogun, awọn ohun tii ma ndi ẹjẹ lara enia yio farahan, wọn a si maa pọ sii ninu ọra inu egungun. Ibiyi ni a o ti sẹda pupọ ninu ẹjẹ ara ọmọ enia.

Biotilẹjẹpe ọmọ inu oyun ti le gbe ara rẹ lati ọsẹ kẹfa lẹhin ti a loyun rẹ, aboyun ma nmọ, fun igba akọkọ, wipe ọmọ inu oun ngberasọ, laarin ọsẹ kẹrinla si ikejidinloogun. Ninu asa abinibi, a npe eleyi ni gbigberasọ.

**Chapter 41 4 to 5 Months (16 to 20 Weeks): Stress Response, Vernix Caseosa, Circadian Rhythms**

Ni ọsẹ kẹrindinloogun, ọna kan ti a ngba ki abẹrẹ sinu ikun ọmọ inu oyun ma nmu ifesi kan waye, eyiti nfa ohun kan ti a npe ni noradirẹnalini, tabi norẹpinẹpirini wọ inu ẹjẹ. Ọmọ ti a ṢẹṢẹ bi ati agbalagba paapa ma nse bayi nigbati ohun ajeji kan ba fẹ wọnu ara wọn.

Ninu ẹya ara ti a fi nmi, ọna ti atẹgun ngba wọnu ara ti dagbasoke daradara.

Ohun kan funfun, ti o wa fun aabo, eyiti a npe ni famisi kasehosa, yio bo gbogbo ara ọmọ inu oyun naa. Famisi yi ma ndaabobo awọ-ara kuro lọwọ awọn ohun ti npanilara, eyiti o wa ninu omira ti o wa ni apo ile-ọmọ.

Lati ọsẹ kẹsan, gbigbe ara, mimi atẹgun sinu, ati lilu ọkan yio bẹrẹ sii waye ni ojoojumọ, ilana eyiti a npe ni lilu ti sakediani.

## Chapter 42   5 to 6 Months (20 to 24 Weeks): Responds to Sound; Hair and Skin; Age of Viability

Ni ogun ọsẹ, apa kan ninu iho eti, eyiti o jẹ ẹya ara ti igbọran, yio ti tobi to ti agbalagba ninu iho eti ti o ti dagbasoke tan naa. Lati igba yi lọ, ọmọ inu oyun yio maa fesi si oriṢiriṢi ariwo.

Irun yio bẹrẹ sii hu lori.

Gbogbo awọ-ara ati ẹya wọn ti wa nipo, pẹlu iho irun ati awọn apo keekeke ti ngbe abẹ awọ-ara.

Ni ọsẹ kọkanleloogun si ikejileloogun lẹhin idapọ, ẹdọforo yio lagbara lati maa mi atẹgun sinu. Ọmọ inu oyun le gbe ile-aye nisinsinyi, nitori pe wiwa laaye ni ode apo ile-ọmọ yio Ṣee Ṣe fun awọn ọmọ inu oyun kan. OriṢiriṢi awọn aseyọri ninu ẹkọ ilera njẹki o Ṣee Ṣe lati mu ẹmi awọn ọmọ ti osu wọn ko pe duro.

## Chapter 43   6 to 7 Months (24 to 28 Weeks): Blink-Startle; Pupils Respond to Light; Smell and Taste

Ni ọsẹ kẹrinleloogun, ipenpeju yio Ṣi soke, oyun inu naa yio si Ṣẹju ni iyalẹnu. Iru ifesi bayi si ariwo ti a pa lojiji ti ma nwaye ni kiakia ju bayi lọ lara ọmọ inu oyun ti o jẹ obirin.

Awọn oluwadi fi ye wa wipe ariwo ti o pọ ju le Ṣe jamba fun ilera ọmọ inu oyun. Awọn ijamba tii ma ntete waiye ni ki ọkan maa mi titi laini idaduro, ki ọmọ inu oyun maa gbe itọ mi ju bi o ti yẹ lọ, ati awọn iwa ojiji miran. Awọn jamba ti maa waye lọjọ pipẹ lẹhin eyi ni ailegbọran daada.

Iwọn bi ọmọ inu oyun se nmi le lọ soke to fifa atẹgun simu lẹẹmẹrinlelogoji laarin iṢẹju kan.

Ni asiko ti o jẹ ipele kẹta ninu igba ti obirin fi nloyun, idagbasoke ọpọlọ ma nlo to idaji ninu gbogbo okun inu ti ọmọ inu oyun nlo. Ọpọlọ yio tobi sii ni iwọn ti o to ilọpo mẹrin si marun.

Ni ọsẹ kẹrindinlọgbọn, oju yio yọ omije.

Ẹyin oju ma nfesi si imọlẹ lati bi ọsẹ kẹtadinlọgọn. Ifesi yi ma nse ilana bi imọlẹ ti ntan sinu ẹyin oju, ni gbogbo ọjọ ti ọmọ naa yio gbe laye.

Ohun gbogbo ti o wulo fun gbigb'oorun nkan ti bẹrẹ sii ṢiṢẹ. Ẹkọ lori awọn ọmọ ti osu wọn ko pe Ṣe akiyesi agbara ati gbọ oorun lati bi ọsẹ kẹrindinlọgbọn lẹhin idapọ ẹyin.

Bi a ba fi ohun ti o ladun sinu omira apo ile-ọmọ, ọmọ naa yio ma gbe itọ mi ju bi o ti yẹ lọ. Sugbọn ọmọ inu oyun kii gbe itọ mi to bi o ti yẹ bi a ba fi ohun ti o koro sinu omira. Ọmọ naa yio fun oju rẹ pọ lẹhin naa.

Nipasẹ oriṢiriṢi awọn igbesẹ bi ti enia ti nrin, ọmọ inu oyun naa ma ntakiti ọbọ.

Ara ọmọ inu oyun naa ki yio wunjọ bii ti atẹhinwa bi ọra Ṣe nkun abẹ awọ-ara rẹ. Ọra nṢe iṢẹ pataki ni mimu iwọn otutu tabi ooru ara enia duro, ati ni pipese okun-inu lẹhin ibimọ.

## Chapter 44   7 to 8 Months (28 to 32 Weeks): Sound Discrimination, Behavioral States

Ni ọsẹ kejidinlọgbọn, ọmọ inu oyun le mọ iyatọ laarin bi nkan Ṣe ndun si ni leti.

Ni ọgbọn ọsẹ, fifa atẹgun s'imu wọ pọ, o si ma nwaye ni iwọn ọgbọn si ogoji ninu ọgọrun igba, lara ọmọ inu oyun.

Ni oṢu mẹrin ti o kẹhin ninu oyun, ọmọ inu oyun ma nhu awọn iwa kan letoleto, laarin eyiti o ma nni akoko isinmi. Awọn iwa wọnyi nfihan bi isẹ ti ọpọlọ ati awọn ka rẹ nṢe ti lagbara to.

## Chapter 45   8 to 9 Months (32 to 36 Weeks): Alveoli Formation, Firm Grasp, Taste Preferences

Nigbati o ba to ọsẹ mejilelọgbọn, awọn iho, tabi apo atẹgun, yio bẹrẹ sii waye ninu ẹdọforo. Wọn yio maa dagba sii titi di igba ti ọmọ naa yio pe ọmọ ọdun mẹjọ.

Ni ọsẹ karundinlogoji, ọmọ inu oyun le di nkan mu giri.

Ohun ti o wa ni ayika ibiti oyun inu ti dagba ma ntọka si awọn ohun ti yio fẹran lati maa jẹ lẹhin ti a ba bii. Fun apẹẹrẹ, ọmọ inu oyun ti iya rẹ jẹ ohun ti a npe ni aniisi, eyiti o fun ounjẹ kan ti a npe ni likorisi ni adun rẹ, fẹran lati maa jẹ aniisi naa lẹhin ti a bii tan. Ọmọ ikoko ti iya rẹ ko ni ohun kan se pẹlu aniisi ko fẹran ounjẹ naa rara.

## Chapter 46   9 Months to Birth (36 Weeks through Birth)

Ọmọ inu oyun yio mu ki irọbi bẹrẹ nigbati ohun kan ti a npe ni ẹsitirogini ba njade lara rẹ, ti o si bẹrẹ ayipada rẹ lati ọmọ inu oyun si ọmọ ikoko.

Rirọbi ma nwaye pẹlu sisunki ile-ọmọ, eyiti yio fa bibi ọmọ.

Lati akoko idapọ ẹyin titi di igba ibimọ ati siwaju sii, idagbasoke ọmọ enia ta yọ, o wa titi aye, o si jẹ ohun ti o diju lọpọlọpọ. Imọ ẹkọ titun nipa ilana ti o fanimọra yi nfi anfaani ti o wa ninu idagbasoke oyun lori ilera ọmọ enia ni gbogbo igbesiaye rẹ han.

Bi imọ wa nipa idagbasoke ọmọ ninu oyun ti ntẹsiwaju, bẹẹni anfaani ti a ni lati jẹki ilera ọmọ enia tubọ fẹsẹmulẹ ngbooro sii- ki a to bimọ, ati bi a ba bii tan.